**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN ẸMÍ ÒKÙNKÙN**

**ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (5)**

**OṢÙ KEJE 2022**

Ìwé Mímọ́ kíkà: Orin Dáfídì 17; 27; 91

Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára tówà nídì àwọn iṣòro mi yóò gbé gbogbo iṣòro mi mìn, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ohun ìjà ọ̀tá, tí wọ́n fi n ṣẹrùbà mi yóò yípadà di ẹ̀rí, ní orúkọ Jésù.
7. Agbárákagbara tó n pa àwọn ohun rere kí ntó mọ̀ nípa rẹ, jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
8. Agbára tó fẹ́ kí nkú lọ́jọ́ alàjá mi, kú, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo ahọ́n tó n gbó lòdì sími, gbẹ, kí o sì kú báyìí, ní orúkọ Jésù.
10. Ẹnikẹ́ni tó n rán ogun sí mi, Olúwa, dá ogun náà padà sọ́dọ̀ wọn, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ogun tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí n dàbí wèrè, Ọlọ́run, pa wọ́n run, ní orúkọ Jésù.

**12.** Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti lé mi kúrò níbi àwọn ibùkún mi, kú, ní orúkọ Jésù.

**13.** Gbogbo ọ̀tá tó n ṣebí ọ̀rẹ́, tó n dámi dúro láti rí irànlọ́wọ́ gbà, idà Ọlọ́run, pa wọ́n, ní orúkọ Jésù.

**14.** Gbogbo àṣẹ àwọn àgbà ìkà lẹ́nu ibòdè lòdì sí ayé mi, ta pàdà, ní orúkọ Jésù.

**15.** Gbogbo agbára ìkà, tó n bà àwọn iyànu mi jagun, idà Ọlọ́run, gé wọn dànù, ní orúkọ Jésù.

**16.** Gbogbo ọfà tó lòdì sí ojúrere kòní bà mí, ní orúkọ Jésù.

**17.** Kọ́kọ́rọ́ òde-ọ̀run, ti gbogbo iṣòro jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

**18.** Ẹ̀mí alàjá tó n ṣe ségesège, kú, ní orúkọ Jésù.

**19.** Gbogbo agbára tó n fikún idàmú lòdì sí mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.

**20.** Àwọn agbára òdì, tó fi ayànmọ́ mi sínú àhámọ́, kú, ní orúkọ Jésù.

**21.** Ọlọ́run dìde, dènà gbogbo agbára tó fẹ́ dèmílọ́nà, ní orúkọ Jésù.

**22.** Atọ́ka-ọ̀nà òkùnkùn tí wọ́n yàn lòdì sími, ká kúrò nípa iná, ní orúkọ Jésù.

**23.** Gbogbo orísun iṣòro nínú ayè mi, gbẹ dànù nípa iná, ní orúkọ Jésù.

**24.** Kinìún Júdà, dìde, jó gbogbo kinìún sátánì tó n rúnú lòdì sí mi run, ní orúkọ Jésù.

**25.** Gbogbo agbára, tó n ró ìbáṣepọ̀ lárin èmi àti ìpọ́njú lágbára, jórun nípa iná, ní orúkọ Jésù.

**26.** Gbogbo ohun rere nínú ayé mi tí àwọn ejò ti gbé mì, ẹ di iná, kí wọ́n sì pọ̀ wọ́n jáde, ní orúkọ Jésù.

**27.** Gbogbo egbòògi àjẹ́, tó farapamọ́ sínú àwọn ìfun mi, jáde, gbiná, ní orúkọ Jésù.

**28.** Égúngún òkùnkùn, tó n fi aìsàn lé mi kiri lójú àlá mi, kú, ní orúkọ Jésù.

**29.** Àwọn ọwọ́ ibi, tó n ju òkúta ìṣóro sínú ayé mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.

**30.** Àwọn ọwọ́ ibi, tó n pèsè pósí lòdì sími, di jíjẹ̀rà nípa iná, ní orúkọ Jésù.

**31.** Àwọn ọwọ́ ibi, tó n dá aṣọ búburú bò mí, jó di éérú pẹ̀lú àwọn aṣọ rẹ, ní orúkọ Jésù.

**32.** Àwọn ọwọ́ ibi, tí wọ́n yàn láti gbé ayé mi sin, jẹrà nípa iná, ní orúkọ Jésù.

**33.** Ẹranko ibi ìyówù, tó n lépa mi lọ síbojì, òpùrọ́ ni ọ́, kú, ní orúkọ Jésù.

**34.** Àyànmọ́ mi tí wọ́n ti gbé sin sínú pósí ibi ìyówù, jáde nípa iná, ní orúkọ Jésù.

**35.** Àwọn agbára tó n pète pèrò láti fún mi ní májèlé jẹ, jẹ májèlé rẹ, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.

**36.** Aṣọ ikú òjijì lára mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.

**37.** Àwọn agbára tó n paradà di igúnugún láti jẹmí run, gbiná, ní orúkọ Jésù.

**38.** Gbogbo ìtẹ́ ibi tó gbé ara rẹ̀ ga lòdì sí ayé mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.

**39.** Gbogbo ọwọ àjèjì, tí wọ́n yàn láti gé àláfíà mi, mo gé ọ dànù, ní orúkọ Jésù.

**40.** Ẹ̀yin ángẹ́lì ogun, ẹ fòpin sí ìfarahàn òkùnkùn nínú ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.